# IROHIN IMỌLE

IMỌLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

NO 874 THURSDAY DECEMBER 17, 1964 (2D)


## "Ko Si Aye Fun Alanişẹşe"

**KANO:- Gbogbo Ile lo kunşọşọ ti ẹsẹ ko si gba ero fun ogunlọgọ awọn Onişowo lọkunrin ati l'obinrin ti gbogbo wọn parajọ sinu Aafin Ọba Kano, Alhaji Ado Bayero ni ọjọ Aiku ti işe ọjọ kẹtala oşu yi.**

Onirohin ni ilu Kano fi ye wa pe Alhaji Bayero ti şe irinajo ọjọ mẹta yi kakiri gbogbo igboro ilu Kano ati agbegbe rẹ lati ba awọn enia ilu Kano sọrọ nipa Owo Ori

Ninu ọrọ rẹ, eyiti o ba gbogbo awọn Onişowo ti nwọn lọ pade rẹ loju ọna sọ nigbati nwọn de inu Aafin rẹ sọ, lẹhin ti nwọn ki ku abọ tan.

Alhaji Bayero şe alaye fun awọn enia na wipe ko si aye ninu ilu Kano fun awọn ọlẹ arişẹmaşe, imẹlẹ ati awọn alapamaşişọ ati ọlẹ.

O wa kilọ fun awọn enia na lati tọra mọ işẹ wọn loju mejeji nitoripe gẹgẹbi o ti şe wi, "Ẹniti ko ba şişẹ, iru enia yowu ti o le jẹ ẹni yowu ti o le bi i ko ijẹ ki iru ẹni bẹ ki o jẹun".

Ninu ipari ọrọ rẹ Alhaji Bayero rọ awọn enia na lati kọju si işẹ wọn ki nwọn o masi şe saya ojule onile ti mọ ibiti ọbẹ gbe dun.

# AWỌN ỌMỌ ONDO KỌ ẸGBẸ DẸMỌ SILẸ !

**ONDO: Gbẹgẹdẹ gbina ninu ipade gbangba ode kan ti awọn ọmọ ẹgbẹ Ilọsiwaju (UPGA) Orilẹ ede Naijiria şe ni opopo oke Lisa ni irọlẹ ana ọjọ Ọjọ 'Ru ti işe ọjọ kẹrindinlogun oşu yi nigbati gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ni Ondo ati agbegbe rẹ pesẹ si ibi ipade na**

Gbogbo wọn lo palọlọ, ti nwọn si ngbọ ijinlẹ ọrọ nigbati Ọgbẹni S. A. Ogundipe, ti işe ọkan ninu awọn Asiwaju ẹgbẹ Alakukọ ni ilu Ondo sọ fun gbogbo awọn enia ti nwọn wa sinu ipade na wipe, awọn ọmọ Ondo ko se ẹgbẹ Dẹmọ awọn ko sifi aye gba igbakugba ni ilu awọn

Gbogbo awọn enia na lo ho gee ti nwọn si tun fo soke fun ayọ pẹlu ariwo 'Awo! Awo!! Awo!!!".

Nigbati Ọgbẹni Ogundipẹ sọ wipe gbogbo awọn enia Ondo patapata, ẹgbẹ UPGA ni gbogbo wọn nşe, lehin ẹgbẹ na ni wọn si wa.

"Ninu ibo ti mbọ yi gbogbo wa ni a o si dibo fun ẹgbẹ UPGA wọle ko si aye fun ẹgbẹ Dẹmọ ni Ondo"

Ọgbẹni Ogundipẹ tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe, "Ibo ti mbọ yi ni yio fi aye ti ẹgbẹ Dẹmọ wa ni Ipinlẹ yi han gbogbo enia"

"Awa gẹgẹbi Ojulowo ọmọ Ondo, ko fi aye gba ẹgbẹ Dẹmọ ni ọdọ wa, bi o tilẹ jẹ wipe tọsan toru ni awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ fi nyọ gbogbo enia lẹnu sibẹ a ko fi aye gba wọn.

"Ẹgbẹ UPGA ti de si ọdọ wa, gbogbo wa si ti tẹwọ gba ẹgbẹ na a si mọ daju pe ẹgbẹ na lo le gba awa ọmọ Yoruba silẹ lọwọ afẹ kajẹ ma fẹ kia yo ẹgbẹ Dẹmọ"



OLOYE AKINTỌLA
Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

Ọgbẹni Ogundipẹ şe apejuwe awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ gẹgẹbi Ọdaran ti o nba ilu jẹ ti o sọ wipe on tun ilu şe

### ỌDARAN

Bakanna ni o tun fi abuku kan wọn wipe Awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti nwa işọkan ati ajọşepọ awọn enia ile yi ni nwọn tun nya awọn ẹya kan sọtọ ninu ilu kan na."

O wa bere lọwọ gbogbo awọn enia ti nwọn wa sinu ipade na lana pe, " Iru işọkan ati ajọsepọonikum wo ni ti ẹgbẹ Dẹmọ bi?

O ni ọpọlọpọ enia ni ohun ti awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ nşe lo yẹ, o wa şe apejuwe wọn gẹgẹbi ẹniti o nhuwa lati tẹ ifẹkufẹ araşe lọrun. ti o si nta enia jẹ pe, ifẹ awọn ara ilu ni on nşe.

O wa fi awọn enia Ondo ni ọkan balẹ wipe ki nwọn o maşe bẹru ki nwọn o si duro jẹ, nitoripe "ọjọ iparun ẹgbẹ Dẹmọ ku si dede, bi awọn ọmọ ẹgbẹ na fẹ bi nwọn kọ."

O wa kesi gbogbo awọn enia na wipe bi ẹgbẹ UPGA ba le wọlẹ ninu ibo ti mbọ yi gbogbo ijekujẹ riba ati owo ẹhin ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ngba kakari Ipinlẹ yi ati iwa ika ati afojudi si awọn Ọba ati Ijoye ni yio de opin."

Gbogbo enia lo kigbe "Awo ! Awo !!" nigbati Ọgbẹni Ogundipẹ sọ wipe "gbogbo ọmọ Ondo ni ko şe ẹgbẹ Dẹmọ, a ko si ni şe ẹgbẹ na, koda, ki Ijọba ẹgbẹ Dẹmọ o ge owo oşu Ọba wa si kọbọ kan, a ko ni şe ẹgbẹ Dẹmọ"

### OWO ABẸTẸLẸ

Ọkan ninu awọn aşiwaju ẹgbẹ UPGA to Ọgbẹni D L Akinọla tun sọrọ ninu ipade na lana tun rọ gbogbo wọn ki o diju şinşin si owo ti awọn ọmọ ẹbgẹ Dẹmọ ngbe kakiri ipinlẹ yi lasiko yi lati ma fun awọn enia ti o ba gba lati şe ti wọn.

O wa bere lọwọ awọn enia na wipe "Fi fun ni owo to. ko to ọmọ enia owo ma a tan, şugbọn iyi ọmọluwabi enia ki tan lailai atipe anfani kini o wa ninu owo ti enia o gba ti Oluwa şe ko si igbadun mọ ?

O tun fi ye gbogbo awọn enia nape "Awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ko ni itiju, owo ni nwọn mọ, nibiyowu ti nwọn ba si gbe ri owo nwọn ko kọ lati de ibẹ

O wa bere pe, "Enia melo lo ti ti nitori owo ẹgbẹ Dẹmọ di ero orun ọsan gangan loni?

O tun sọ wipe, "Bi nwọn ba tun da ẹgbẹ miran silẹ ni Ipinlẹ yi loni, ti awọn ọmọ ẹgbẹ Demọ ba gburo owo nibe, nwọn şetan lati tun fi egbe Demo sile ki nwon o si tun ma a ba ẹgbẹ titun na lọ"

O wa rọ gbogbo awon enia na lati ma tani nwọn papa julọ awọn ọmọ Yoruba ki awọn o maşeta ara wọn fun awọn enia miran nitoripe, Bi a ba'ta ara ile ẹni ni ọpọ a ki iri i ra lọwọn mọ, ẹgbẹ Dẹmọ fẹ ta awọn ọmọ Yorube si ẹsu nitori owo



DOKITA OKPARA
Olori Ẹgbẹ Alakukọ

Nigbati ọgbẹni Akinnola nsoro yi gbogbo awon enia na lo tẹti leko ti ẹnikan ko le wo ẹnikeji loju depo ti won o pariwo bi awon en a na ti şe pọ to.

Onirohin wa ni Ondo fi ye wa wipe awon enia ti o wa ninu ipade na le ni ẹdẹgbẹrin (7,000) enia.

### AWỌN ỌBA

Ọgbẹni Akinnọla wa kesi gbogbo awọn Ọba Ijoye ni Ipinlẹ yi

WO OJU EWE KẸFA

## IPADE UPGA

Awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA yio şe ipade loni ni deede agogo marun irọlẹ ni opopo Great Bridge niwaju Iga Olorogun

Awọn ti o wa ni Ebute- Mẹtta yio şe ipade ti wọn ni Abule Ijẹsha ni agogo marun kanna

Nwọn npe gbogbo ọmọ ẹgbẹ lọkunrin ati l'obinrin.

Tete ra Irohin Imọlẹ tirẹ lọla ki o ba le mọ ibi ti wọn ma ti şe ipade ti ọla.

# AWOLỌWỌ D'ORIṢA (Apa10)

Mo ti mọ ọ gẹgẹbi ọga ninu iṣẹ agbẹjọro. A jọ ṣe ṣe olukọni ni Ile Ẹkọ Giga ti awọn Ijọ. Metodist; o ti ṣe Olotu Ijọba Ipinlẹ ti o ti ṣe ọpọlọpọ nkan rere ti ẹnikan ko ṣe ri. Iwọ ẹniti o ti bẹrẹ si jiya lati kekere.

## Lati Ọwọ Adio Mọsanya



**Oloye Obafẹml Awolọwo**
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Anu ṣe mi pupọ. Ṣugbọn ẹri ti a jẹ ninu kota yi ni mo ni lati tẹle O b e r e pẹlu ẹri Ọmọwe Ọgbẹni Onabamiro gẹgẹbi mo ti sọ lasiko, nko ro pe enia bi Ọgbẹni Adedipẹ le sọ ọrọ ilodi si ọ nitoripe Ijẹbu kanna ni yin.

Nko fi igba kan ro pe emi yio ṣe idajọ fun ẹniti o ti ṣe olori Ijọba Ipinlẹ ati olori Alatako Ijọba O dun mi pe ko si ohun ti mo le ṣe lẹhin igbati mo dajọ ẹwọn fun awọn ọmọde wọnyi.

Nitorina, iwọ na yio ṣe ẹwọn ọdun mẹwa fun ẹsun ti a fi kan ọ"

Bayi ni Awolọwọ di ero ewọn l' ọsangan.

Awọn onisọkusọ le wipe ọrọ ẹniti o ti gun kan 'giti Awolọwọ sọ. Ṣugbọn ohun kan ni loju: mi gbo-gbo idamu Awolọwọ, ko ṣe ohun alebu kan. kan. Awo ti fi han gbangba pe larin ida, asalẹ ati ẹranka buburu iwa rere ko le di eru lailai Ibukuu ni awọn nkan ti mbọ, ti sọ 'ni di okunrin." 'ọpọlọpọ ni iponju olododo, ṣugbọn Oluwa yọ ninu gbogbo wọn O pa egungun rẹ mọ; ẹyọ kan ko si yẹ "Jẹki nku iku olododo, si jẹki igbẹhin mi dabi tirẹ."

### IBANUJẸ NI FUN ABUBAKAR TAFAWA BALEWA

Ọrọ ti o si ti ẹnu Ọlọla Abubakar pe o ba on ninu jẹ pe a ju Awolọwọ s'ẹwọn ati pe o jẹ "nkau ẹdun fun ilẹ Naijiria, jade bi ohun rere ti a ko nireti. "Ohun ti ọkan nro ni ẹnu nsọ jade Bi kiba ṣe pe inu ni ibanujẹ Ọlọla Abubakar ti wa, mba sọ pe iwa agabagebe "Ko si ohun ti o dun lati ṣe ju ki enia fi ibanujẹ ti ko de 'nu han" Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ri ohnn ẹyẹ yi ninu iwa Olotu Ijọba apapọ eyi ni orun sọpẹ: Ọ k a n Balewa mọ, agbari rẹ ni nkan misan wa Ko gba Awo l' asiko kan rara lati ri, ki o si sọ eyiti o dura lara ọta rẹ jade.



Alhaji Abubakar

## Ọmọ Ọlọrọ Iṣiwaju Ti o Nta Ilẹkẹ Fun Ọloro Ikẹhin

Lati Ọwọ Omidan MULIKATU OYERỌGBA

Ni igba atijọ nigbati enia ko gbọn pupọ, Iya kan wa ninu ilu kan (lẹba Ọdan) ti o njẹ Agbaṣepẹlẹ Iya yi a ma jẹ Ṣekorowo o bi ẹgbẹrun ọmọ, ninu awọn ọmọ na ko si eyi ti o gbayanju lati ṣe iṣẹ ninu wọn. Nwọn ti gbabe pe iṣẹ ni ogun iṣẹ. Ṣekorowo yi ni owo gidigidi.

Ninu ilu kanna yi, Iya kan tun wa ni'bẹ. Iya yi ko ni owo ṣugbọn ati jẹ ati mu ko wọn. Iya yi bi ọmọ kan ṣoṣo ọmọ na njẹ Aiyedun Iya Aiyedun foro rẹ lati ri pe o ko iṣẹ Aiyedun kọ 'ṣe o yege, o si jẹ idunnu iya rẹ pe on ni ọmọ ti o yege.

ṣekorowo pẹlu awọn ọmọ tirẹ njẹ nwọn nmu, nwọn ti gbagbe ye iku mbẹ ki ng ma ba opo lọ sile oloro. Ni ọjọ kan iku wọle Ṣekorowo di ara iiẹ, awọn ọmọ rẹ wa di ẹniti o nwoju le onişegun kiri. Nwọn bẹrẹ si sare boba ko mu boba ko bu lẹsẹ. Ni kukuru nwọn pa ara wọn ku mẹfa Awọn mẹfa wọnyi şi pin gbogbo ẹru Iya wọn. Ohun ti a ko ba jiya fun şe ki le tọjọ ohun ti a ba fi nra sisẹ fun ti npẹ lọwọ ẹni.

Ọkan ṣoṣo ọga ṣebi o sanṣẹ ẹgbẹtala irunu ọmọ Ni ọjọ ti Iya Aiyedun di ara ilẹ gọngọ ṣọ gbogbo ilẹ mi titi. Aiyeduu fi ogo iṣa apa rẹ hen. A ti ara apa tẹ dide. şebi ko le mọyi ọ t a Ẹniti o ti fi gbogbo agbara rẹ şişẹ ni ọjọ aiye iya rẹ. ni Aiyedun nta, o nra lẹhin iku iya rẹ o si njẹ ọpọlọpọ ere. Ki a ma fa ọrọ gun lọ t ti Aiyedun tubọ ndi Ọlọla ati Ọlọrọ ni arin ilu agbaṣepẹlẹ.

Lotitọ niwura pẹlu fadaka ni ye lori ṣugbọn ikan ti o ntan ni ọdun egun gẹgẹbi a ti ṣe mọ awọn baba wa ni o ma nsọ wipe Oluṣesi ina ko tan owo ṣugbọn owo ti enia ba ni le ti o kan nna, ti ko şisẹ kun, njẹ dandan kọ ni ko fi idi kan lẹ awọn ọmọ Ṣekorowo ti ọwọ bọ owo, nwọn bẹrẹ sina laipẹ owo owo tan, nwọn bẹrẹ si ta awọn ohun ini wọn. Ọpọlọpọ ninu awọn ikan ini wọn ni nwọn ta fun Aiyedun nigbati ikan ini wọn tan nwọn di ero oko nwọn bẹrẹ si ṣẹ igi ta Nwọn wa jo'ye ọdagba sẹgi ta ti o ṣe oge tan l'ewe

Nitori eyi ẹyin enia mi ẹ jẹki a fi owurọ ojọ aiye wa sişẹ ki a ba le fi ọjọ alẹ wa sinmi. Ninu wahala a nlọ o'o a mbọ yi ni awọn ọmọ ṣekorowo mẹfẹfa yoku si ti Aiyeadun ti o ti fi owurọ sişẹ sun pẹlu irorun si ori itẹ bi Ọba.

Nitori ki o ba le yẹ wa lọjọ alẹ, gbogbo ikan ti a bi mu ni owurọ şe, ko yẹ ki a ma sọ di ọjọ alẹ. Ẹ jẹki a ranti pe iṣẹ ni ogun Ẹ ma fi owurọ şere ọjọ nlọ.

# Akunleyan Ni Adaiye Ri

## Lati Qwọ Ẹsọ

Nigbati ara wa mbẹ ni ẹMi li ode ọrun, Olodumare fi si etigbɔ wa wipe, ki a ma mura, nitoripe, a nlọ si ibẹ iye igba eti akoko bayı ni a o si gba oibẹ ki a to pada wa.

Nibẹ ɾ purọ va nibẹ ika wa nibẹ ılogun wa e l e pe wa a j ẹ wa osɔ wa clu sin Ọlọrun, olorişa eleşu wa olowo wa ọlọrọ wa Talaka wa ẹlẹgbẹ wa Alaşọ wa ọba wa ijoye wa Alaşẹ wa Alaasan wa ati orişirişı kan bawọani lo mbẹ nile a ı y e ni ti o gbe nlọ na lọ ki o lọ yan eyiti o ba wun ọ

Ki nıo ma ba ọrọ Akunleyan ẹda yi lọ mọ kọkọ fẹ fi ti awọn Irunmọlẹ lode ọrun şe apẹrẹ fun eyin ọkawe wa bi o ti jẹ wipe, ohun ti kọ jọ ni l'ju lo nse ọşẹ nla to, Olodumare pe gbogbo awọn molẹ ọrun jọ, o ni ki nwọn joko, ni soju wọn li o şe mu esupe ti, o si fi şe ẹda enia, Olodumare gbo e palẹ, o ni ki awọn Mọlẹ ọrun ma lọ wo, ki nwọn si kọ ọgbọn nipa rẹ şugbọn ki enikan mase ba ise ọwọ on jẹ.

Iyalẹnu ni eyi jẹ fun awọn Mọlẹ nigbati Olodumare sọ pe ki nwọn ma jọ kọ gbọ lara enia nitori pe nwọn ro ninu ara wọn wipe iru ọgbọn wo ni awọn yio kọ lara enia ti a fi erupẹ şe ẹda rẹ. nwọn mọ oruko ti a npe ile ko si si ara ti nwọn ko le fi da nitorina nwọn pẹgan ọrọ,

Ẹ lẹgbara, şunmọ enia, o bɔre si fi ọwọ te kakiri ara bi o ti fi ọwo tẹ enia ni agbẹdu nibiti Olodumare gbe fi ti si bẹni ọwọ rẹ jin sinu gburu o yọ owọ rẹ lojiji, o si salọ Apa ibi ọwọ rẹ ti ọjo n ni a npe ni Iwọ tabi Idodo gbogbo awọn Mọlẹ ọrun salọ nwọn ko si fẹ lati de ibi ti enia gbẹ wa mọ,

WO OJU EWE KARUN

# Yẹ Irawọ Rẹ Wo

AQUARIUS (Jan 22 . Feb 20) Sọra pupọ lakoko yi kio ma ba ju nkan olowo iye bi ye nu.

PISCES (Feb 21 - Mar 20) Iwọ yio ri nkan ayọ ati idunnu iwọ o si sọ gbogbo ibanujẹ rẹ di ayọ.

AIERS (Mar 21 - April 20) Ohun ayọ yio wọ ile rẹ wa loni mura silẹ fun idunnu.

TAURUS (April 21 - May 20) Ohu ti oti nda ọlamu, yio salọ kuro m şe jafara.

GEMINI (Mar 21 - June 21) Iwọ yio sorire, sugbọn wahala diẹ ko ni salai wa irin ajo kan ti yio seọ ni anfani mbẹ lẹsẹ rẹ.

CANCER (June 22 - July 22) Jẹjẹ ni akoko yi gba ni'orina iwa ijẹjẹ ni ki o hu

LEO (July 23 - Aug 22) Ire ni ọjọ oni jẹ fun ọ, ma se lo ire na ni ilokulo, iwọ o gbọ irohin lati okere, ati la ti ẹnu iyawo rẹ kan

VIRGO (Aug 23 - Sept 23) Isẹ rẹ yio ma lọ daradara bi iwọ ko ba se aseju.

LIBRA (Sept 24 - Oct 23 Oni lati yanju ọrọ kan ti od ju iwọ yio ri ranlowọ nipa re.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Gbogbo awọn enia pata kiti oh lo b sọrọ loni, ni iwọ yio ma ri oju rere w n.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Orisirisi ero lo mbẹ li ọkan re sugbon iwọ ko mọ ibiti iwọ ogbe gba.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 21) Bi o ba nfẹ ki oba orire pade, oni lati lọgbọn lori ki olọ fi ọrọ we ọrọ lọdọ ọrẹ rẹ

# IDIJE ! IDIJE.

A fi eyi kede fun awọn Onkawe Irohin Imọlẹ ati awọn Ọmọ karọ-o-jire pe a nfẹ

## ITAN L'EDE YORUBA

Eyiti ẹnikẹni ko ti tẹ jade ninu iwe ri tabi ti nwọn ko ti sọ lori ẹrọ Redio ri Ẹnikẹni ti o ba si bori yio gba

**(£5)** PỌNUN MARUN

Akiyesi;- Kọ itan tirẹ ki o ha ı rekete, ti ẹniti ko bi han a o fa ya ni, ki o si mọ dajudaju pe ko ni ipa ninu Idije na, ITAN ẹniti o ba si daraju a o tẹ jade ninu Iwe Irohin Imọlẹ yi a o si fi lọ(£5 Posta Order) ranşẹ si

Fi Stamp Tọrọ (3d) ranşẹ fun gbigbe Pọnun marun (£5) ti o ba jẹ pada si ọ. K o ge ibiti Idije yi wa, ki o si fi ranşẹ pẹlu Stamp tọrọ rẹ si wa. Ẹnikẹni ti ko ba ge Idije tirẹ ranşẹ siwa ti o ba jẹ owo na a ko ni fi ranşẹ si.

Orukọ.............................................

Ibugbe.............................................

...................................................

Fi itan rẹ ranşẹ si:-

**Olotu Irohin Imọlẹ**
16, BAMGBOSE STREET, LAGOS.


## Gbanjo ! Gbanjo ! !

F N ỌDUN KERESIMESI

A ni lati fi kede fun awọn onibara wa pe Ọja gbanjo wa bẹrẹ lati oni lọ titi di 30/11/64. Tete ra tirẹ ki o to kase nile

APEJUWE ILE ITA IWE WA

Wọ Bọosi Mushin, sọka'e ni Atẹ ọlara Bus Stop Bere ladipọ Street ti o ba rin titi Ladipọ, bere ILE IWE ODU - ABỌRE. Ti o ba de ibẹ tan, wa be re Nomba 5, Alaba Stree Mushin, ile işẹ wa dojukọti ODUS SURF"

AWỌN ỌJA WA

Olubori Egbogi Ajẹbidan 40s di 30s Iwe Egbogi Ajẹbidan 25s di 22s Iwe Egbogi Awogba Aruu 20s di 17s Iwe Ilana Ifa purin titẹ ati etu şişe 20s di 17 Iwe Afọsẹ Isẹdalẹ Yoruba ati Psalmu Ajẹbidan 3/6 di 2s 6d Turari Isegun Aje 10s 6d di 8s Turari Itaja 10s di 6d 8s Turari Ala rere 10s 6d di 8s Iye owo Turari pangolo biti oke yi Turari ti o wa ninu paketi jẹ 2s 6d pere Iwe Itumọ Ala Joseph Alala 5s Iwe Aniyan eto Irun o ti di 2s 6d Akọnni lesin pataki Islam 2s 6d Tailor's Measurement book di 1s 6d

Tenants Agreement Forms 10/6d di 5/ Gold Smith Forms Certficate of Apprenticeship (mẹta) 17/6 di 10/6d

ỌJA TITUN TI A ŞẸSẸ RI GBA

Abẹla mimọ fun adura tete Idalọju (orişirişi awọ pu Turari.

bẹla mimọ fun it j (Kowe wole pẹlu Turar 20/-

„ „ „ Işegun . pẹlu Turari 20 -

Lọfinda tabi Ororo ipara fun itaja, Işegun Ajẹ ati arisiki 30/- Igo kan

Fi owo ranşẹ tabi ki o wa ra ni ọdọ:—

J. O. Shoyinka
Alaba Street
5. MUSHIN.

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIC

ALE-BI-ALE Egbogi Tọniki Jamanu tituo ti gbogbo ara ilu Eko ati Jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan isẹ rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala şişe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi awọn işan ara rẹ gbogbo ko ba şişẹ daradara ti Eemi Breath) inu rẹ ko ba gunlẹ daradara fun işẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo' tabi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mọ daju pe "DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ la'i sọ'ara rẹ di ọtun pa tapata ara rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ tio ti hunjọ yio yi po padapatapata alafia ati gbadun yio de si ọ Iyẹn bẹ.



Bere egbogi na ni Şọbu

NIGERIAN MEDICENE STORES
4, Tinubu Square Lagos
Waterloo Medicine Stores,
8, Palm Church Street, (Ọja Ita Faji
Lagos, Nigeria.
ADEDUN CHEMIST
14 Wakeman Street Yaba

---

**Kini F. Nduro Fun ?**

Bi o ba ni asọ fun fifọ ati lilọ bi ( wollen ) asọ oke, Tapẹta Sapeti ati orişirişi asọ ti o ba n fun fifọ ati lilọ ni i-eju kan

TETE GBE WA SI ỌDỌ

**JOYCE LAUNDRETTE SERVICE**
**34, Ojo — Oniyun Street,**
**Apapa Road Ebute Mẹtta**

Kia ni ao ba ọ fọ ti o si ri gba ni ẹsẹ kanna. A le wa gba ni ile rẹ, ki a si ko pada fun ọ ti a ba fọ tan kọ nomba ile rẹ ranşẹ si wa.
Dan wa wo lẹkansoso ki o si ri bi işẹ wa ti dara to owo pọọku ni a si ngba

---

**Polowo Ọja Rẹ 'Ko Ti Yege**

*Nitoripe*

O KO TI POLOWO OJA RẸ SINU

**IROHIN IMỌLẸ**

T'ODUN KA FUN GBOGBO YORUBA

KỌWE LỌ WO ỌJA RẸ SI

ADVERTISMENT MANAGER

**IROHIN IMỌLE**

16, Bankole Street Phone 2,985

# ỌWE SI OLOTU

## Adegbenro Ma Şe Bẹru.

Olotu, Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ lati kesi Adele olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Alhaji D. S. Adegbenro lati mura si işẹ to nşe lati şe ẹhin olori ẹgbẹ rẹ ti ko si ni aye lati şe iru eto ti Alhaji Adegbenro nşẹ bayi Şugbọn ki o ma şe wo ẹhin rara nitori işẹ to nşe yi lo le mu olori ẹgbẹ wa Oloye Awolọwọ jade kuro lọgba ẹwọn lasiko idibo to m ọ yi



Alahji D. S. Adegbenro

Awọn ọmọ ilu Abeokuta si tun wa lẹhin ọmọ Adegbenro ati pe ohun ti ẹgbẹ le şe ti rara nitori eyi mo rọ Alhaji Adegbenro ki o ma şe wo ẹhin tabi ki o ma şe bẹru adun ni yio jẹ tirẹ ni ikẹhin igbẹhin ni alayo nta nk n ti gbogbo awa ọmọ ile Yoruba mọ daju pe iwọ Alhaji Adegbenro ni yio bọ wa di Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria laipẹ eyi si da wa loju ati pe o pẹ larin oşu meji ọdun ti a o bọ si yi. Olotu mo dupẹ pupọ ajinde yio ma jẹ o.

Emi ni,
Adekunle Lawal,
ABẸOKUTA.

## Ajegunlẹ Nfẹ Amo juto Ọlọpa

Olotu Jọwọ gba mi aye diẹ ninu iwe nyin oloyinmọmọ to nta bi akara gbigbona lati keşi ọga agba awọn ọlọpa ilẹ Naijiria je wa ni ngbegbe Apapa Ajegunlẹ lati wa ri si awọn Ọlọsa ti ko jẹ ki a simi lọsan ati loru to jẹ pe a ko le fi ẹru wa si ile ti a ni

Eleyi yio dun mo awa olngbe ilugbe inu Ajegunlẹ pupọ bi ọga agba awọn Ọlọpa yi ba lo ipo rẹ rere lati ba wa dẹkun iru awọn olọşa wonyi paapa julọ ni ọru eyi tọ je ako le sun gb dun.

Ọpọlọpọ awọn to lasọ ni awọn ti so di alakisa ati pe eleyi yio dara bi awọn ọlọpa ba le ma se abojuto agbegbe ti mo darukọ rẹ lọsan ati loru lati le fun awa ti yio ti lo si ibi işẹ wa losan ni abo lo dara fun awon duk'a ti a fi si ẹ lo Olọtu mo dupẹ pupo.

Emi ni
Deji Ọlatunji
AJEGUNLẸ.

## Mo Ki Ọmọ Adimula

Olotu Jọwọ gba mi ni aye diẹ lati kansaara si ọrọ ti Ọgbẹni wa lọgbọn ati ọjọgbọn ninu ọrọ nipa bi awọn ẹgbẹ oselu wa ti nlọ si mo tun ki ọmọ Adimula fun alaye ti o sọsinu iwe irohin Imọlẹ ti ọjọ kesan osu yi'

Nigbati mo ka ọrọ Ọgbẹni mi yi omije si mbọ loju mo lọsẹkẹsẹ ohun to fa ọgbẹni ọjọ lo si sọ ninu oro gba a mi ọrọ rẹ na patapata şugbọn gbogbo ohun ti Ọlorun ni papọ bi enia ba nl igbagbọ si ọro Ọlorun bi ki ẹnikan ni otilo ati ododo gbogbo oro ati ireti ni yio ma jẹ

Mo tun fẹ so fun omo Ademula pe bi a ba di ibo tan pe emi ifẹ lati wa mọ Ile Ifẹ ati on na papa Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi ọko Ọba ki ni şa oyin l sẹ Amin.

Emi ni
A. Ileseinde
SHOMOLU

## Ẹjẹ Ki A jina Fun Ẹgbẹ Dẹmo

Olotu mi ọwọn, Alafia fun yin ati fun gbogbo Oluka iwe yin oloyin mọmọ yi lati kesi gbogbo olu gbe Naijiria ni apapọ ati olugbe Ipinlẹ Iwọ Orun ni pataki lati jina si awọn ẹgbẹ Ọdọlẹ Dọmọnu N N DP ki a ma ba di ẹrun ọsan gangan.

O yẹ ki a fi oju inu wo iru aşe ori ikumọ ti nwọn gbe le ori awọn Olugbe Ile sha Ikaiẹ ati Ogbomọsho nje ti awọn Ẹgbẹ yi ba şeşi wọle ibo nje a o le rin ni ilu mọ bayi.

M fẹ ki oni a uku wa ki a r nti işesi wọn Olu r Ẹgbẹ sọmọdẹru vi i nkan bi Ọdun 1945 1962 ti 1964

Ki Oluwa ma şọ wa dẹru ọsan gangan ni ilẹ baba wa yi o

Emi ni
Ganiyu Kọla Jubirila
MUSHIN

# Akunlẹyan Ni Adaiye Ri

## Lati Oju Ewe Kẹta

O si tun ṣe ni akoko kan ati igba kan. Olodumare tun pe awọn Mọlẹ ọrun, o ni ki nwọn lọ sile aiye, nibiti awọn enia yio ma gbe, ki nwọn lọ wo o, bi o ti dara to, ohunkohun ti ko ba si ye nwọn, ki nwọn bere lọwọ on, Ni gbogbo awọn mọ ẹ ba ṣi gangan o di ile aiye nwọn bẹrẹ wo awọn ohun ti a fi sọ ile aiye lọjọ, nwọn ko ri ohun kan ti o jọ wọn loju, nwọn ri, ewe, omi, okuta, orişirişi okuta yanrin: Idẹ, Wura, fadaka orişirişi eso igi, Awọ Sanmọ, ọrun oşupa. ati Irawọ Ina ati orişirişi awọn nkan ni işọri-ṣọri.

Nigbati o ṣe ni nwọn kan oke lala ọmọ ntẹgbẹja nwọn fi ọwọ kanfa; nwọn si ri gẹgẹbi o le to, nwọn bere lọwọ Olodumare wipe, awọn ri oke nla ni, njẹ ohun kan yio ha wa ti yio ni agbara ju oke yi lọ bi ?

Olọdumare dahun pe o Irin lagbaraju oke ti ẹ ri ni lọ. Awọn mọlẹ sare lọ si ibiti yanriu kusa gbe wa, nwọn yio bi o ti ri yẹtuyẹtu. Nwọn tun bere pe, njẹ ohun kan ha tun mbẹ ti o lagbara ju irin ti a ri yi lọ bi ? Olodumare dahun pe Ina lagbaraju irin ti ẹ ni yi lọ.

Awọn Mọlẹ sare lọ si Aja ilẹ nibiti na nla gbi wa ti o njo bulabula, nwọn tun bere, pe, njẹ ohun kan wa ti o lagbara ju ina ti a ri yi lọ bi? Olodumare dahnn wipe, omi lagbare ju ina ti ẹ ri yi lọ. Nwọn rọgiri, o di inu Okun. a,

Nwọn tun bere wipe njẹ ohun kan ha mbẹ ti o lagbaraju omi lọ bi ? Olodumare dahun wipe, o mbẹ, efufu lagbaraju omi

Nigbẹhin nwọn tun bere pe, njẹ ohun kan ha tun mbẹ ti o lagbaraju efufu lọ bi ? Nigbana ni Olodumare dahun pe ko si ayafi enia.

Nigbana ni gbogbo mọlẹ ti nju ba fun enia.

---

## Disu Ṣe Iranti Oloogbe Sẹlia

Eko;- Lẹnu lọlọ yi ni Iyaafin Adiat Ajibọla (Adiat Disu) ṣe iranti oloogbẹ iya Sẹlia ni ile rẹ, 11 Kosọkọ Street, Ẹsẹ awọn Oniwuridi Mọsalaşi Iya-Alaşọ Ole ni o si pe şibẹ şọşọ ęsẹ awọn ẹbi Disu l'Ojogun ni o si pe sibẹ bakanna.

Alhaji Mukadani Ra fu ni o ṣe isin-akanşe Alhaji Onim wu ati Alhaji Salmonu Are si ran an lọwọ Adiat na wabi-wọsi owo, o si fi orişirişi onjẹ adidun tẹ awọn ti o pe sibẹ lọrun Awọn ẹbi Disu, awọu bi Alhaji Y. A Disu, Alhaji Kudira Disu, Ọmọ Ọba Mojisọla Ashafa Tijani Sidikatu Tashala a'i Shoyibatu Disu si fa ọmọ yọ Isin iranti okn na wu. ni lori pupọ, ki Ọlọrun pa aşişe oku na rẹ, ki o kẹ ẹ ki o si gẹ ẹ, Ki o da awọn ọmọ rẹ si, ki o ma ṣe atilẹhin fun wọn ni gbogbo igba.

---

## ADURA JẸ J'OGUN LỌ

Iwe Adura patiki fun Aris ki lati lẹ Mesira 2/6
Iwe Adura Akanşe ati apẹrẹ ile aiye........ 2/
Afọmọ - isin Ojişenla Muhammed........ 1/
Iwe Itumọ al ati Adura Ala Ibanujẹ........ 3/6
Iwe Aniyan Irun ojojumọ ati Aniyan pataki fu Musulumi 1
Tete fi Owo ranşẹ si:-
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue, Lagos Naijiria
(Leti Ọja Jankara l'Eko)

---

# EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBOGI



Aworan ẹgbẹ yi fihan gba gba ibiti Jẹdijẹdi rẹ wa ni ara rẹ ti nyọọ lẹnu nigba gbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi iho idi en ibiti a ma ngba şe igbọnsẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun ọkunrin ti o si soro pupọ lati şe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni o wa ti nta kakiri ode nisisiyi ana nwọn ma a npolowo nwa un iwosan rẹ şugbọn bi fale i ri mẹ va ninu awọn gun ti o lẹ şe iwosan arun CYCLOVEN

iy daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya ki wọn gbe lọ si Ile iwosan lati lọ e eyiti o ba nyọ jẹde omusu ku nipa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patpata.

Şugbọn awa ko ro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakanna Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa Ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma şe igbọsẹ dede tabi lojojumọ ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pupọ ojojumọ abi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwu ẹran Şuga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba Jẹdijẹdi orisirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyó sode ninu omuşu tabi ti o ba nmu ẹjẹ walẹhin igbọnsẹ tabi ti o ba nyọ ti o ba şe igbọnşẹ tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuşu ni eyikeyi ti o ba jẹ bere egbogi CYCLOVEN ati awọn Oyinbo Jamani şẹşẹ wa idi rẹ kio si danwọ kuaju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de ba ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo awọn ti ie tanigboro Naijiria bere ni :

NIGERIAN MEDICINE STORS
4 Tinubu Square Lagos
WATER-LOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone :- 22678 Nigeria, (Ọja Ita faji
ATI NI ŞỌBU
OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN.

EGBOGI AWỌN ARA ILU FARANSE

# TESSYDRE

Fun Ọmọ — Ọwọ Ati Ọmọde Gbogbo

Tessydre jẹ ojulowo egbogi haunhaun ti mbji irufẹ bẹ kosi kakiri igboro ilu Nigeria fun itọju ọmọ ọwọ tabi ọmọde lati le jẹ ki wọn ma hu ẸHIN ẹnu wọn pẹlu irọrun laisi wahala rara tabi aikole sun yala losan tabi sun awọn iya wọn gbogbo Ogorun orisirisi egbogi bayi ni wọn npolowo sinu erọ gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumọ şugbọn kosi eyi ta le fi we egbogi Tessyd re rara o. Ọlọgbọn di ori ẹja mu pupọ ninu awọn ara ilu Saro ati awọn ara ilu Agonyin (CHANA) mọ egbogi yi dajudaju on na ni wọn si nlọ fun awọn ọmọ ti wọn ba şẹşẹ bi titi fi di nkọn bi ọmẹ ọdun wawa gbako. Kosi wahala tabi iyọnu inu rirun ọka ori inu iwọ aiperi osiinu fẹkun fekun ewo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ şişu, gburu tabi aikolokun ninu ara sisu, Inu kunkun iro afẹfẹ ati orişirişi awọn amodi tabi aisan ti o ma nyọ awọn ọmọ ọwọ lẹnu ni ba Ehin HIHU" gbogbo. Tessydre a ma mu ki ehin ẹnu rẹ ọmọ rẹ lagbara gidigidi ati Isan ara wọn pẹlu.

Awọn ọmọ ti wọn nlo egbogi yi ki saba şe ami rara niwọn igba ti wọn ba ti ngbọsẹ dede, ti otutu ko si le ri aye lati duro ni igbaya wọn ti wọn jẹun dara dara ti nwọn si nsun gbadun pẹlu

Bere Egbogi Ni Şọbu Awọn:—
WATERLOO STORES
8, Palm Church Street, Lagos
ADEDUN CHEMIST
4, Wakeman Street, Yaba

# IROHIN IMOLE

*MOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA*

No 874 THURSDAY DECEMBER 17, 1964 [2D)


## Ọkunrin Kan Lu Iyawo Rẹ Pa

AGBANI:- Ọrọ di pẹẹntuka nigbati ọkunrin kan, bẹrẹ si ba iyawo rẹ ja ija aja kuakata, ti iyawo rẹ na si subululẹ lojiji ti o si fi bẹ di ero ọrun lọsan gangan ni ọjọ Aiku ti işe ọjọ kẹtala oşu yi ni Agbani, Ilu kan ni Ipinlẹ Ila oru Naijiria.

Irohin awọn ọlọpa fi ye wa wipe, Obinrin na, ti işe ẹni ẹdun mejidilọgbọn, e wa ninu oyun oşu mẹrin, on ati ọkọ rẹ ni nwọn si dijọ ja ija na.

Ohun ti a gbọ wipe o da ija na silẹ ni wipe, iyawo na nşe oju meji, ko si tun şe olotitọ si ọkọ rẹ pẹlu oyun osu mẹrin na.

Nigbati ọkọ rẹ ri ohun ti nsẹlẹ si obinrin na ni ojojumọ bere ọrọ na lọwọ iyawo rẹ, eyiti o dija larin awọn mejeji, nibiti o ti nlu iyawo rẹ pẹlu ibinu iyawo na wolu lẹ lojiji o si fi bẹ di ero ọrun.

Lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo awọn ara ile ba salọ ki awọn ọlọpa to de.

Awọn ọlọpa ti mu ọkọ obinrin na,nwọn si ti gbe oku iyawo rẹ lọ si ile iwo s a n lakulaku fun ayẹwo awọn Dokita.

Oluwa rere, gba wa lọwọ iku ojiji o.

# ỌKỌ RELUWE KAN TAKITI SINU ODO LALUPỌN!

## Şugbọn Ko Si Enia Ti O Sofo Ẹmi Ninu Ijamba Na!!

**IBADAN:- Ariwo nla ta, okiki ijaiya si kan lati Lalupọn titi de igboro ilu Ibadan ni titi de igboro ilu Ibadan ni afẹmọnjumọ ana ojo Ru ti ise kẹrindinlogun osu yi nigbati oko reluwe kan ti o nko ẹru lo si Ọffa lati Eko takiti sinu Odo Lalupon.**

Irohin ti a ri gbọ lati ọdọ oniwe Irohin wa ni Ibadan lẹhin to lọ wo ibi ti işẹlẹ na ti şe tan fi ye wa wipe lati Eko ni ọkọ Reluwe na ti mbọ, Ọffa ni o si fẹ gbe ja gbogbo awọn ẹru ti o wa ninu rẹ silẹ.

Nigbati ọkọ reluwe nade ori gada lati kọja odo Lalupọn, ni irin ọkọ reluwe ti o wa lori gada na ti ọkọ reluwe gbe nkọja ba şẹ simeji ni ojiji ti ọkọ na si takiti sinu odo.

Idaamu nla ba awa ọkọ reluwe na ati awọn osişẹ ọkọ na tọbẹ ti nwọn ko fi mọ bi aiye ni awọn wa mọ tabi ọrun ni

Awọn Ọlọpa ọkọ reluwe fi ye Onirohin wa wipe, ọkọ ẹru ni ọkọ reluwe na, ko si awọn ero ninu rẹ, ẹru nikan pere lo wa ninu ọkọ reluwe na ni a s i k o şẹ'ẹ buburu na.

Lẹsẹkẹsẹ ti iş.lẹ na de si etigbọ awọn ọga ọkọ reluwe na, ni gbogbo wọn ba sare fi ohun ti nwọn nse silẹ gbogbo wọn şi sare lọ si ibiti isẹle nla na ti şẹ,

Nigba ti nwọn de ibẹ, nwọn ri wipe ko si ẹniti o şofo ẹmi ninu awọn osişẹ inu ọkọ a, şugbọn awọn ẹru diẹ to wa ninu ọkọ na şegbe. " gbogbo awọn ọkọ ti o mbọ wa si Eko lana ko ri ọna kọja ni Ibadan, bẹ i awọn ọkọ reluwe ti o kuro l,Eko lọna ko ri ọna Kọja bakanna.

Awọn osişẹ ọkọ reluwe ti bẹrẹsi şe atunşe oju irin na lati gbe eyi to bajẹ kuro ki nwọn o si gbe omiran si.

Ati lati tun gbe ọkọ relulu na kuro ninu odo pada si oju irin.

A gbọ wipe, işẹ atunşe na yio gba wọn to ọjọ meji ki o to le pari.

A lero pe işẹ oju ọna na yio pari loni tabi ni ọa awọn ọkọ yio si ma ri ọna kọja

Onirohin wa kan ran wa leti pe eyi ni igbakeji ti ọkọ reluwe yio subu sinu odo yi.

## Ẹlẹmu Kan Jabọ Lati Ori Ọpẹ

**BANSARA-: Idaamu nla ba gbogbo awon enia ti nwon enia ti nwon wa ni Basira, ilu kan ni agbegbe Ogoja ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria nigbati Ọkunrin kan, Mbum Ediel ti o nşişẹ ẹmu jabo lati ori Ọpẹ ti o si ku bamubamu ni ojo Aje ti işe ojo kerin a oşu yi.**

Irohin awọn ọlọpa Ogoja lọ si oko ẹmu lati lọsişẹ rẹ gẹgebi o ti şe ma nsẹ ni ojojumọ. Ọpẹ kansoso na lọ si şẹku ti yio gun ni ọjọ na ki o fi ma lọ si ile

Bi o ti nşare gun Ọpẹ na lọ, ti o si ku diẹ ki o de ori rẹ lati da ẹmu ori Ọpẹ sinu akerengbe ti o wa lọwọ rẹ ni ọwọ rẹ ba tase ti o si subululẹ.

Nigbati ọkunrin na subululẹ, oyi lọ si isalẹ o si fi ọrun şẹ. Nigbati awọn enia rẹ ko ri ni nwọn ba lọ fi ọrọ na han awọn ọlọpa ni Teşan.

Sugbọn nibiti awon ati olopa tima okunrin na halisi ninu igbago ni idi ope ti osi ti ku bamubam .

Awon olopa ti gbe oku okunrin na lo si ile iwosan lakulaku ni ogoja fun ayẹwo awon dokita.

Agbo wipe gbogbo awon onibara rẹ ti won nduro de ni sọọbu rẹ wọn fẹ ra ẹmu nigbati won reti rẹ titi ti won ko ri ni gbogbo won ba tuka lọ.

## Awọn Ọmọ Ondo Kọ Ẹgbẹ Dẹmọ Silẹ

LATI OJU EWE KINI

pe nwọn lọ şe pẹlẹpẹlẹ pẹlu ẹgbẹ oşelu nitoripe baba ni awọn Ọba wa jẹ fun ẹgbẹ Yoruba ti o le wa lori aga akoso Ijọba.

Ni ipari ọrọ rẹ, Ọgbẹni Akinlọla ni on mọ dajupe inu awọn Ọba wa gbogbo ni k o da s i gbogbo ohun nşẹlẹ ni Ipinlẹ yi şugbọn ẹru mba wọn lati sọ jade, ki owo oşu wọn o ma ba şe di kọbọ kan lọdun


### Ogun Belubelu Tabi Lẹrẹ

ỌNA ỌFUN — ỌNA ỌRUN

Ewu nlanla ni lati fi abẹ si ọfun lati ge Belubelu oti şe iku pa ọpọlọpọ enia nipa bayi ati kan Ogun Ajẹbidan ti ati fi wo Ogun n'ọgọ enia san ni ọjọ kan na.

Ko Si Tun Se Oluwarẹ Mọ Lailai,

Ẹ BERE LỌDỌ

**Ọgbẹni Aro - Lambo**

43, Koseh Street, Lagos.

A DAYS REMEDY FOR THE CURE OF

**TONSILITIES**

WITHOUT OPERATION

**Price 12s 6d**



Printed And Published by Modupẹ Printing Press, 16, Bamgboşe Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos (17/12/64)